# Idagbasoke


| | Akoko | Oju Ewe |
|---|---|---|
| AWON OBIRIN ATI ODO | | |
| **Merkel lo di olori egbe oselu ni orile-ede Germany** | **1min. 6secs.** | **6** |
| *Igbese ti iru re ko waye ri kan ni orile-ede Germany fi obirin se olori egbe oselu to nse ijoba lowolowo.* | | |
| **Awon obirin ile Afrika ni a fojusi ninu Ipolongo lati tako ifi-iyato-si** | **2mins. 30secs.** | **18** |
| *Awon akitiyan titun lati pa ifi-iyato-si to nkoju awon obirin ile Afrika re ni o bere ni ilu Nairobi* | | |
| **Awon obirin orile-ede Spain wo inu iwe itan.** | **51secs.** | **21** |
| *Awon obirin lo je olori ni ile asofin agba ati kekere ninu ijoba orile-ede Spain nisisiyi.* | | |
| **O setan ko setan: Awon odo orile-ede Naijiria ni ohun lori ero asoromagbesi redio.** | **2mins. 51secs.** | **22** |
| *Ere ori itage titun kan lori redio dojuko awon nkan to nsele lowolowo to je koko fun idagbasoke orile-ede Naijiria.* | | |
| **Ifojusona fun Beijing and marun** | **1min. 30secs.** | **23** |
| *Igbaradi fun Apejo nla ti awon obirin ti yio waye ni ilu New York.* | | |
| **Awon Ijoba dahun si Iwe Iwadiotito** | **1min. 35secs.** | **24** |
| *Awon orile-ede nfi iwoye won ranse lori oro awon obirin.* | | |
| **A yan alaga titun fun Igbimo Eleto** | **1min. 14secs.** | **24** |
| *Omo ile Afrika ni o je alaga fun igbimo to nseto Apejo nla ti Beijing ati marun.* | | |
| **Eredi Beijing ati Marun?** | **1min. 30secs.** | **24** |
| *Kini awon koko ifojusona si ninu ipade na?* | | |
| OUNJE | | |
| **Won ti ri igbado to nle kokoro olubaje danu** | **1min. 49secs.** | **8** |
| *Won ti se awari eya agbado kan to nle kokoro abagbado je to banileru danu.* | | |
| **Won se awari Iresi iyanu** | **2mins. 33secs.** | **13** |
| *O seese ki awon idagbasoke enu ojo meta yi ninu imo ero nipa ajogunba iseda ohun alaaye se iranwo lati gbejako ebi.* | | |
| **A nfe iranlowo fun awon olufaragba iyan** | **1min. 9secs.** | **10** |
| *Bi opo eniyan sii ni orile-ede Ethiopia se ni idojuko ebi beni a nteramo ipe fun iranwo lati odo awon orile-ede agbaye.* | | |
| AWUJO | | |
| **Monomono nkolu orile-ede Ethiopia lekeji** | **3mins. 4secs.** | **18** |
| *Orile-ede na tun ni idojuko iyan elekeji laarin odun medogun si ara won.* | | |

**Ijoba tiwantiwa gba alekun ni orile-ede Senegal** **1min. 12secs.** **22**
*Fun igba akoko lati odun 1960, idibo yi ijoba pada ni orile-ede Senegal.*

ETO EDA ENIYAN
**Orile-ede Algeria silekun sile fun awon egbe ajijagbara fun eto eda eniyan** **1min. 42secs.** **9**
*Ipe wa si orile-ede Algeria kan ti won ti nbere fun lemolemo tele ni o mu inu awon egbe fun eto eda eniyan dun.*

**Eto Eda Eniyan ni ile Afirika** **1min. 48secs.** **23**
*Aibale okan lo soke laarin awon ajo ti ko lowo ijoba ninu nipa ipo ti eto eda eniyan wa ni ile na.*

ORO AJE
**Orile-ede Germany ngbero lati fagile gbese orile-ede Mozambique** **57secs.** **10**
*Omiyaleyaona ati ipadanu emi ti se okunfa igbese kan lati fagile gbese ti orile-ede Mozambique*

**Iderun Gbese fun orile-ede Tanzania** **41secs.** **20**
*Irapada oro-aje orile-ede Tanzania gba alekun.*

**Orile-ede Japan mu Eto Iderun -Gbese gbooro si** **1min. 6secs.** **16**
*Orile-ede Japan ti se alekun eto iderun-gbese re si ilopo meji.*

**O seese ki won ma le fi koko orile-ede Naijiria sowo si ile okeere mo laipe yi** **47secs.** **21**
*O seese ki ikuna lati tele awon ofin kariaye ni ikolu lori atita okan ninu awon ogunna gbogbo ohun ogbin ti a nta si ile okeere.*

**Ajo Agbaye fun Idagbasoke fe se idasile akojo-owo fun Imukuro osi ni orile-ede Naijiria.** **1min. 19secs.** **21**
*Awon akitiyan atungbedide lati pa osi run ni orile-ede Naijiria gba alekun.*

ILERA
**Eroja ajogunba eya eda alaaye se alekun ewu arun okan ninu awon to nmu siga** **1min. 19secs.** **20**
*Iwadi siwaju sii se ifesemule ikilo Dokita Oniseabe Agba lori taba.*

**Ogbeni Bill Gates gbe milionu metadinlogota owo dola amerika sile lati fi gbejako arun kogboogun eedi.** **1min. 55secs.** **20**
*Okunrin to lowo ju laye se igbeowosile to poju titi di oni yi lati fi gbejako arun apani na.*

**Egbogi agbejako kokoro bakteria le se idena awon ikolu to je mo Kokoro-Arun HIV.** **1min. 42secs.** **15**
*O seese ki Cotrimoxazole, egbogi agbejako arun iredodo fukufuku funni ni ojuutu olojo-kukuru ninu itoju awon ikolu to je mo Arun kogboogun Eedi.*

| | | |
|---|---|---|
| **O seese ki imole Oorun fa arun ebo-oju**<br>*A ti ri ilowosi orisun pataki fun agbara ina ni agbaye ninu okunfa arun pataki kan.* | **1min. 34secs.** | **16** |
| **Erekusu Taiwan yio se ifojusi Igbonriri ati Eya Ile apani ninu ibere lati di omo egbe Ajo Agbaye fun Oro Ilera.**<br>*Orile ede Taiwan tun se itiraka miran lati wa ninu Ajo Agbaye fun Oro Ilera.* | **1min. 56secs.** | **21** |
| **Asewo pelu taba igbo yio bere lori awon alaisan**<br>*Ilo taba igbo lati koju irora to ga lara awon alaisan ni yio bere laipe.* | **1min. 34secs.** | **16** |
| **O seese ki aseyori lori egbogi kan se iranlowo fun iranti opolo ninu awon arugbo**<br>*Egbogi titun le mu ki opolo awon agbalagba sise pipe bi ti awon odo.* | **1min. 48secs.** | **17** |

## *Ayika*

AFEFE ILE

| | | |
|---|---|---|
| **Ojuutu si imoorusi-aye ko si ninu agbara ina Nuclear**<br>*Ajo WWF tanmo lilo awon orisun agbara to wa lona to dara si to si mu alafia wa dipo ninawo lori agbara ina nuclear to lewu pupo.* | **3mins. 7secs.** | **6** |
| **Awon atole ibori-igbo teereteere nse idinku isodiasale ni orile-ede China**<br>*Orile-ede China ni ipinnu lati bori ogun re si isodiasale to nwonuilebo.* | **1min. 16secs.** | **7** |
| **Awon Orile-ede G-8 si ni ireti fun Adehun lori Ayika**<br>*Egbe eleni-mejo na ngbe igbese lati fi owo si adehun pataki kan lori imoru-si-aye.* | **2mins. 37secs.** | **17** |
| **Imorusi ile Arctic nmu irokeke ewu ba awon eye**<br>*O seese ko je wipe awon eye ni imorusi aipe yi ti won se akosile re ni ile Arctic yio mu irokeke ewu ba julo.* | **3mins. 23secs.** | **8** |

EDA ABEMI EGAN

| | | |
|---|---|---|
| **Orile-ede Egypt ati Thailand gba awon eru ehin erin to po**<br>*Isigunti airotele laipe yi si awon onisowo ehin erin ni orile-ede Egypt ati Thailand fihan wipe owo ti ko bofin mu na si ngberu - eyi jasi ori buruku fun awon erin ile Afirika.* | **2mins. 33secs.** | **13** |
| **Ajo CITES dabobo eja aye igbaani**<br>*Ipade Ajo Agbaye to sese pari fi eya miran to wa labe ewu iparun kun akosile re.* | **3mins. 59secs.** | **10** |
| **Igbesele isowo ninu ijapa okun si wa sibe ni orile-ede Cuba**<br>*Orile-ede Cuba kuna ninu itiraka re lodo Ajo CITES lati gba isowo laaye ninu awon ijapa okun re.* | **2mins. 59secs.** | **11** |

| | | |
|---|---|---|
| **Ajo CITES fi ake kori wipe igbesele isowo ninu ehin erin gbodo tesiwaju**<br>*Igbesele isowo ninu ehin erin si wa biotilejepe awon orile-ede die faramo isowo labe ofin.* | **2mins. 45secs.** | **12** |
| **Orile-ede Australia fi ehonu re han lori pipa ti orile-ede Japan npa abuibutan**<br>*Orile-ede Australia nparowa fun orile-ede Japan wipe ki o ma mu iwadi re ninu eyiti o ti npa abuibutan gbooro si.* | **2mins. 15secs.** | **12** |
| **Ogba awon eranko kan ni orile-ede China yio ya orile-ede Amerika ni beari panda meji**<br>*Ogba Eranko ti orile-ede Amerika to wa ni ilu Washington ni yio gba beari panda meji gegebi ara akitiyan lati gba awon beari panda nlanla na la.* | **1min. 47secs.** | **19** |
| **Abuibutan to gunle si eti okun ni orile-ede Japan ti ku**<br>*Abuibutan kan to won to iwon toonu medogbon ni o ku ni etikun arigbungbun orile-ede Japan biotilejepe akitiyan lo lati wakati-de-wakati lati gbaala.* | **1min. 22secs.** | **19** |
| **Awokose SAVANNA fi imole titun han lori iwontunwonsi laarin eda abemi egan ati eda eniyan**<br>*Agbekale awokose kan lori ero komputa yio le sotele iru awon ayipada ti yio wa ninu ayika Ila-oorun Afirika to takoko, yio si se iranwo lori awon ipinnu lori itoju iseda aye.* | **1min. 43secs.** | **15** |
| OMI MIMO ATI OMI OKUN | | |
| **Isakoso ati Ilana lori oro Omi ni awon agbegbe ologbele**<br>*Apero nla kariaye kan ti kepe fun idasile igbimo alagbara kan lati bojuto owongogo omi ni awon agbegbe ologbele.* | **1min. 31secs.** | **19** |
| **Orile-ede Amerika nkepe fun Adehun Aabo lori Omi Agbaye**<br>*Orile-ede Amerika tanmo idasile ifowosowopo aabo kan ni agbaye lati saami Ojo Ile Aye.* | **1min. 15secs.** | **6** |
| **Awon Afenifere ayika gbe igbese lati se italaya si awon iwe pelebepelebe to so wipe ohun ti a le mo ko ni eya ara eja dolphin ninu.**<br>*Awon afenifere ayika tapa si ofin kan to tun le tubo fi emi awon eja dolphin sabe ewu.* | **3mins. 1sec.** | **9** |
| IDOTI AYIKA | | |
| **Idoti ayika ni a ti fi esun kan wipe on lo fa ipadanu agbeka kurukuru fun idabobo ofurufu ni ile Arctic.**<br>*Idoti ayika ti eda eniyan nfa ni o nni ikolu to buru jayi lori agbeka kurukuru fun idabobo ofurufu ni ile Arctic.* | **1min. 57secs.** | **7** |
| **Ajo Greenpeace bori ijakadi lati dena ikojade eru aloku ohun ose nuclear**<br>*Ase ile ejo kan ti dena igbiyanju lati ko aloku alotunlo ohun ose nuclear lati orile-ede Faranse lo si orile-ede Belgium.* | **1min. 27secs.** | **7** |

## *Ifojusi:*

**Aseyori Iwadi**
*Awon idagbasoke enu ojo meta yi ninu iwakiri fun ilana eto emi ninu itupale eya ara eda eniyan.*

**Awon Onimo ijinle Sayensi se agbejade awari lori bi emi se bere.** **2mins. 8secs.** **14**
*Imo denudenu si itupale eya ara eda eniyan le je awari ti yio yi aye pada.*

**Ifojusona si osu kefa fun itupale ajogunba eya ara eda eniyan** **2mins. 42secs.** **14**
*Akoko ti aye yio ka "iwe emi" nyara bo kankan.*

## *Eto Awon Omode*

**Bi Ketekete Abila se gba awon ila re.** **3m ins. 22secs.** **24**

## *Oro Asokagba*

**Awon oro manigbagbe lori ayika ati idagbasoke** **25**

# IROYIN

**Orile-ede Amerika nkepe fun Adehun Aabo lori Omi Agbaye 1min. 15secs.**
Akowe Agba fun orile-ede Amerika, Madeleine Allbright ti tanmo idasile ifowosowopo aabo kan lori omi agbaye. Eyi je idahun si awon rogbodiyan ti ologun ati ti oloselu to le waye lori owongogo omi.

Ninu oro re to ka lati saami Ojo Ile Aye ni ilu Washington. Allbright so wipe awon isoro to jemo omi nmu ikalara to ga wa lori Eto Imulo lori Oro Ile Okeere ni awon agbegbe to gbelege ni aye. O se afikun wipe orile-ede Amerika yio kopa asiwaju ninu agbekale ifowosowopo titun na.

Gegebi oro re: "Ohun ti mo ni lokan ki ise ifowosowopo bi Ajo NATO eyiti o wa fun awon orile-ede kan ...... sugbon ifowosowopo ti ko mu kanpa wa eyi to si sile fun gbogbo awon to ba moye bose se pataki to lati sise papo lati toju omi to lo lati orile-ede de orile-ede, ki a sakoso re pelu ogbon, ki a si lo daada."
*The Guardian*

**Merkel lo di olori egbe oselu ni orile-ede Germany 1mins. 6secs**
Oloselu ti ila-oorun orile-ede Germany tele ni won ti dibo yan gegebi olori titun fun egbe oselu Christian Democrats ni orile-ede Germany. On lo ropo olori ijoba teletele Helmut Kohl, eyi si so di okan ninu awon obirin die to wa ni awon ipele to ga julo ninu ijoba ni ile alawo funfun Europe. Yiyan re ni a ri gegebi idagbasoke rere ninu idande awon obirin to nlo lowolowo ni gbogbo aye.

Arabirin Merkel to je omo odun marun-din-ladota ni oloselu akoko lati ila-oorun orile-ede Germany tele to di olori egbe oselu na to je egbe oselu to se pataki julo lehin ogun ajakaye keji. Gegebi oro to so nigbati o ngba awon itanna leyin idibo na, "mo dupe lowo yin fun atileyin yin mo si ni ireti wipe yio lo fun igba pipe."
*The Guardian*

**Ojuutu si imorusi-aye ko si ninu agbara ina Nuclear 3mins. 7secs.**
Awon ogbon imulo to peye lati se idinku awon efin alagbara lati inu igbejade agbara ina ilentriki eyi to nfa imorusi-aye ko gbodo da lori agbara ina nuclear. Eyi wa lara iroyin kan lati owo ajo Akojo Owo ni Agbaye fun Iseda Aye (Worldwide Fund for Nature (WWF) eyi ti a se agbejade re lati owo Ajo Ifitonileti ni Agbaye lori Agbara Ina (World Information Service in Energy) ni ilu Paris.

Iroyin na so wipe piposi agbara ina nuclear ko yorisi ilosile itujade efin oloro $CO^2$ - to je ogunna gbongbo efin alagbara to nfa imorusi aye. Eyi jasi be ni apakan nitoripe igbarale awon ero agbara ina nlanla ma nse alekun ilo ina ilentriki dipo ki o se igbelaruge imudarasi ninu ipese ati ilo agbara ina to munadoko.

Iroyin na woye wipe agbara ina nuclear ma ngbe ina ilentriki nikan jade, nigbati o je wipe opo ninu agbara ni a nilo gegebi igbona. Eyi jasi wipe a o tun ni lati jo afikun awon ohun idana lati inu ile, eyiyi yio se alekun itujade efin oloro $CO^2$ de ipele kanna gegebi apapo igbona ati agbara ina to nlo efin alagbara fun idana.

Jennifer Morgan to je Oludari Ajo WWF fun Ipolongo lori Iyipada Afefe Ile so wipe "awon ijoba ko gbodo fi aye gba igboriyinfun agbara ina nuclear. Akosile ilana na gbogbo je keke fun imuwasaye ayipada titun ati ti imugborosi oja fun awon orisun agbara ina to mo to si munadoko nitoto."

Awon orile-ede alagbara-ina Nuclear bi Canada, Faranse ati Japan ti nse ipolowo agbara ina nuclear fun awon orile-ede to si ndagbasoke. Sugbon apeere orile-ede China ti fihan wipe sise imudarasi imunadoko agbara ina je ona to dara julo fun awon orile-ede to si ndagbasoke dipo agbekale agbara ina nuclear. Siso ina

lo ni orile-ede China yorisi wipe orile-ede na yera fun itujade iwon ogbonlenirinwo milionu toonu efin oloro $CO^2$ laarin odun 1980 ati 1997.

Iroyin na tesiwaju lati ya aworan okoowo agbara nuclear gegebi eyi to ti nlo sile. Ko ni anfani oro aje mo latari igba gbogbo eniyan laaye to ti gbile ninu okoowo agbara ina. Eyi tun ribe latari itekuro ni lilo awon ile ero agbara ina nlanla si awon ile ero agbara ina kekeke to nlo efin alagbara, to si nmunadoko, ati ti idije agbara ategun to sese nyoju. Isoro iwalalafia to nkoju okoowo agbara ina nuclear na tun lowosi ilosile ninu igbajumo orisun agbara ina yi.
*WWF*

**Awon atole ibori-igbo teereteere nse idinku isodiasale ni orile-ede China 1min. 16secs.**
Itankale awon atole ibori-igbo eyiti a se idasile re ni ekun Jilin to wa ni iha ila-oorun ariwa orile-ede China ni o ti se iranwo lati din awon ile ti isodiasale nda laamu ku lati milionu meje o le iko meta ninu mewa saare hektari si milionu meji o le iko marunleladota ninu ogorun.

Ekun na se ifilole ise agbese atole ibori-igbo pataki merin lati odun 1990 lo. Laarin odun mejo to koja, ekun na gbin saare hektari ile igi egberun lona ogofa. Eyi si se alekun ibori igbo iko mewa o le die si iko mejila o le die ninu ogorun.

Isodiasale je okan pataki ninu awon isoro ayika to dojuko aye, to si nmu irokeke ewu ba emi awon eniyan to ju edegberun milionu lo. Ni orile-ede China, iko merindinlogun o din die ninu ogorun gbogbo ile won ni o ni ikolu isodiasale eyi si nlo soke pelu egberun meji ibuso kilomita lododun.
*The Guardian*

**Ajo Greenpeace bori ijakadi lati dena ikojade eru aloku ohun ose nuclear. 1min. 27secs.**
Ile ejo kan ni orile-ede Belgium ti dena idapada eru aloku ohun elo ohun ose nuclear ti won se ayipada re lati orile-ede Faranse si orile-ede Belgium nitori orile-ede Belgium ko ni awon eto nipa ijamba oko oju irin.

Ile ejo dajo ni igbelese iwe ehonu ti ajo Greenpeace ko lati jirebe fun gbigbesele kiko eru na lati ibudo atunlo to wa ni La Hague ni orile-ede Faranse nitori awon egbe ajafitafita lori ayika na salaye wipe orile-ede Belgium ti kuna lati se agbekale eto pajawiri fun ijanba ninu irin-ajo na.

Eru na ni yio je akoko ninu medogun iru re lati ko awon aloku lati ile ero agbara ina nuclear ti orile-ede Belgium ti won ti fi ranse si ariwa orile-ede Faranse fun ayipada. Orile-ede Belgium gbero lati gba iwon mita onigun merin marun-din-logorin aloku ti won ti fi igbona nla so di gilasi, iyen ni awon epo idana ti won ti se ayipada re ti won si ko sinu agolo fun itoju fun ojo pipe. Aloku na yio si lewu pupo fun opolopo orundun.
*CNN.com*

**Idoti ayika ni a ti fi esun kan wipe on lo fa**
**ipadanu agbeka kurukuru fun idabobo ofurufu ni ile Arctic. 1min 57secs.**
Igba otutu gigun kan ni ile Arctic fa okan ninu awon ipadanu agbeka kurukuru fun idabobo ofurufu to si poju ninu akosile. Gegebi awon onimo ijinle sayensi lati ajo NASA ati Ajo Isokan Ile Alawo funfun Europe se so, idoti ayika lati owo eda eniyan lo fa.

Awon iwon ti awon oluwadi won fihan wipe agbeka kurukuru idabobo ofurufu na to wa ni ekun Arctic ti dinku pelu bi iko ogota ninu ogorun laarin osu kini ati idaji osu keta. Awon imo miran ti oko inu ofurufu gba gbe eyi lese. Idinku agbeka kurukuru idabobo ofurufu ti a se akosile re ninu odun yi fihan wipe awon eroja kemikali

'chlorine' to wa ninu awon idoti ayika kan si nrababa ni iha ariwa to jina. Die ninu awon eroja kemikali 'chlorine' yi le ba agbeka kurukuru idabobo ofurufu ile aye je ti won ba wa ninu otutu to ga pelu itansan oorun - gegebi o se sele ni akoko otutu yi.

Biotilejepe igbejade awon idoti yi ti dinku, ti eyi si din iye kemikali 'chlorine' to wa ninu ofurufu ayika ku, ipadabosipo kikun ti agbeka kurukuru idabobo ofurufu ni ekun Arctic ko le waye fun opolopo ewadun.

Iroyin na tun woye wipe idinku agbeka kurukuru idabobo lori ekun arctic yi ti fa idinku die ninu agbeka kurukuru idabobo ni gbogbo iha ariwa aye eyi to lo lati ariwa ile Europe titi de ariwa orile-ede Amerika.
*CNN.com*

**Imorusi ile Arctic nmu irokeke ewu ba awon eye 3mins. 23secs.**

Nibayi, Ajo Akojo Owo fun Iseda Aye (Worldwide Fund for Nature) ti kilo wipe o seese ki ayipada ninu afefe ile ge akojopo awon eye to wa ni ile Arctic si idaji.

Pelu ilo awon awokose afefe ile, awon onimo ijinle sayensi lati Ibudo Iwoye Itoju Iseda Aye ni Agbaye se agbeyewo awon ikolu igbonatutu ati idinku ibugbe lori awon eye to wa ni ekun arctic.

Awon oluwadi na ri wipe ninu orundun to koja lo, igbonatutu ni aye lo soke pelu iko mesan ninu mewa ipele Farenheit kan. Ko si ibomiran ni aye ti imorusi na ti farahan pupo ju ti ekun arctic lo nibiti iwontunwonsi igbonatutu ti lo soke to ipele meji ati iko meje ninu mewa ipele kan Farenheit laarin ewadun kokan lati odun 1960. Laarin adorin si ogorun odun to nbo, awon onimo ijinle sayensi sotele wipe akojopo efin oloro $CO^2$ ninu ayika le di ilopo meji. Awon olugbe arctic ni yio wa lara awon eni akoko lati fi ikolu iyipada afefe ile na han.
Iroyin na kilo wipe awon igbonatutu to ba ga soke le fa awon igbo onigi lati sun soke si iha ariwa ki o si ropo ile perese ti ko ni igbo (tundra), eyi to je agbegbe ibisi to se pataki fun egbegberun lona egbegberun awon eye.

Lara awon eye-omi ekun arctic ti imorusi aye fi sabe ewu julo ni a ti ri pepeye-odo alaya pupa eyi to wa labe ewu to ga pupo, pepeye-odo ti ewa *tundra*, pepeye-odo *spoon-billed* ati pepeye-odo *emperor.*

Pelu ilosoke igbonatutu laye ti ko ju ipele kansoso ati iko meje ninu mewa ipele farenheit nigbati yio ba fi di odun 2070, gbogbo awon eye yi lo le padanu idaji ibugbe won. Eyi to ju iko meji ninu meta gbogbo pepeye-odo ati eyi to fere to iko marun-din-logorun ninu ogorun eye ako ti a ni ni ekun arctic. Iwadi na sotele wipe ipadanu iko ogoji si marun-din-logota ninu ogorun ile perese ti ko ni igbo (tundra) laarin orundun to nbo yio yorisi ipadanu ibugbe fun milionu marun pepeye-odo ati milionu meje ati abo eye ako.

Awon oluwadi na ko wipe: "Iwadi yi tun se ifesemule bi o se se pataki to lati se idinku awon itujade awon efin alagbara to nfa imorusi aye ki a si din iye bi afefe ile se nyipada ku ni kiakia. Lati le mu iyirapada si afefe ile to yipada wa, a ni lati fi iyipada ninu isakoso ibugbe sinu ero ni kiakia."
*ENN*

**Won ti ri agbado to nle kokoro danu 1min. 49secs.**

Bi eya agbado ti a mo si B-96 tile tinrin pelu igi ti ko lagbara ati itakun ti ko dagba pupo, o ni ohun kan ti awon eya agbado miran nfe. Eya agbado na lati orile-ede Argentina ni won ti se awari wipe o ni kemikali kan to ndi abo kokoro abagbadoje ti ile Europe lowo lati y eyin.

Gegebi oro Bradley F. Binder to je onimo ijinle sayensi nipa awon kokoro to si wa pelu ile ise iwadi lori ise ogbin ti orile-ede Amerika se so, “Ijakadi pelu kokoro abagbadoje ile Europe na ti le fun awon agbe, paapa awon to nsogbin lailo tabi to nlo die pere ninu awon egbogi ipakokoropaeku onikemikali. Kokoro abagbadoje ile Europe yi a ma na awon to ngbin agbado ni orile-ede na ni owo to to adota-din-nirinwo milionu owo dola Amerika lododun. Laisi kemikali tabi awon ona itoju miran, awon ipadanu na le ju bilionu (milionu lona egberun) kan owo dola Amerika lo.

Nisisiyi awon olugbin ma nlo agbado ti a ti fi imo ero ajogunba eya gbe jade lati ni awon kemikali to npa awon omo kokoro, sugbon agbado B-96 ni kemikali oludabobo kan to nse idiwo fun abo kokoro abagbadoje lati ye eyin. Nibayi agbado onimo ero ajogunba eya na ti a mo si *Bt* ndi awon omo kokoro lowo lati pa jade kuro ninu eyin ti a baye.
*CNN.com*

**Awon Afenifere Ayika gbe igbese lati se italaya si awon iwe pelebepelebe to so wipe ohun ti a le mo ko ni eya ara eja dolphin ninu. 3mins. 1sec.**

Awon afenifere ayika ti ro adajo orile-ede Amerika kan lati da ijoba Aare Clinton lowo ko ki o ma le so iwe pelebepelebe orile-ede na to njeri wipe ohun ti a le mo ko ni eya ara eja dolphin ninu di yepere nipa jijeki won lo fun awon eja tuna ti won fi awon ko pelu eja dolphin ti won ju sile. Eyi ni ohun to tun sese yoju ninu ija ti ofin ati ti oloselu olojo pipe. Fun odun mewa o le die seyin, awon oko apeja to npa eja tuna to ba fe iwe ijerisi pelebepelebe na ni won dena re lati maselo awon awon alakopo nla to nko eja tuna po mo eja dolphin to ma nwe pelu awon eja tuna onilebe alawo ofefe ni iha ila-oorun okun nla pacific.

Ile igbinmo asofin koko gbesele iru ipeja be ti awon oko orile-ede Amerika ba se ni odun 1972, won si wa fi ofin kanna de awon oko ipeja ile okeere to nko eja wasi orile-ede Amerika. Awon idajo ateyinwa ti fi agbara sii fun awon ilana to kepe fun igbesele oja lati awon orile-ede ti ko kun awon oju osuwon na.
Lilo iwe ijerisi pelebepelebe na yio yipada lati osu kerin odun nigbati eka ile ise ijoba fun okowo gbero lati fi aye gba eja tuna ti awon oko apeja orile-ede Mexico ba pa lati gba iwe ijerisi na niwongba ti awon oluwoye lori awon oko na ko ba ri wipe a pa eja dolphin tabi pa eja dolphin lara ninu awon awon alakopo na.

Oro na ti pin awon afenifere ayika si meji. Awon egbe bi ajo Greenpeace ati Ajo Akojo owo fun Iseda Aye (Worldwide Fund for Nature) fi ara mo ofin odun 1997 kan to gbe igbesele kuro lori eja tuna ti a ba kopo pelu eja dolphin. Ofin gbani laaye lati lo iwe ijerisi na fun awon eja ti won pa eyiti Ile ise ijoba orile-ede fun Ipeja ninu okun ko ri wipe o pa awon dolphin lara. Lara awon to pejo na ni Egbe orile-ede Amerika fun Idena Iwa Ika si awon Eranko (American Society for the Prevention of Cruelty to Animals) ati Egbe Alanu (Humane Society).
*CNN.com*

**Orile-ede Algeria silekun sile fun awon egbe ajijagbara fun eto eda eniyan 1min. 42secs.**

Ninu ayipada ojiji kan ninu eto imulo, Aare orile-ede Algeria, Abdeaziz Bouteflika, ti pe awon egbe ajijagbara fun eto eda eniyan merin lati be orile-ede re wo. Eyi je ayipada eto imulo to bere ise ni odun 1992 eyi to dena awon egbe ile okeere lati wo orile-ede na lati se iwadi lori iteloju eto eda eniyan lakoko idite awon elesin musulumi.

Ni odun 1999 orile-ede na ko gba awon omo orile-ede Amerika alanu to fe wa se iwadi awon esun ifiyajeni ati pipa eniyan danu lati owo awon omo ogun ijoba.
Titi di isisiyi, bi egberun mewa enia loti ku ninu iwa ipa na to bere ni odun 1991. Ijoba ti debi iwa-ipa na lori

awon onijagidijagan esin musulumi to dihamora. Sugbon sa, awon iroyin wa to fihan wipe awon omo ogun ijoba na ti hu awon iwa ipa ninu eyiti awon ara ilu ti ku.

Ni ilu Paris, aare Ajo Alasepo Kariaye fun Eto Eda Eniyan (International Federation of Human Rights) ti tewogba isele titun na eyiti o fi aye gba awon egbe ajifitafita fun eto eda eniyan lati wo orile-ede Algeria.

Iwe ipe na ni a gbe jade ni ojo'ru ni oruko Aare Bouteflika ni ile ise orile-ede Algeria si Ajo Agbaye ni ilu New York.
*Times*

**A nfe iranlowo fun awon olufaragba iyan** **1min. 9secs.**
Awon ajo kariaye fun iranlowo nlakaka lati ri wipe opo iranwo sii ni o de agbegbe ti a npe ni iwo Afirika nibiti awon milionu mewa eniyan wa labe ewu iyan eyiti o waye latari ogbele olojogbooro.

Ni okan ninu awon ibiti oro na kan ju, iyen ekun Ogaden ni gusu Ethiopia, ajo agbegbe kan fun iranlowo royin wipe omo mefa ti ojo ori won ko to odun marun lo nku lojojumo. Agbegbe Gode ati awon ayika re ni awon oku eran-osin kun kakiri.

Ajo Agbaye fun Eto Ounje (UN World Food Programme) ati awon ajo miran ntiraka lati se ipese ounje fun awon to nilo re sugbon iroyin nso wipe awon akitiyan won lo nni idena latari awon titi ti ko dara. Awon iroyin tun so wipe awon olote ati awon adigunjale ti nsi lo si awon agbegbe ti iyan na kan.
*CNN.com*

**Orile-ede Germany ngbero lati fagile gbese orile-ede Mozanbique** **57secs**.
Minisita orile-ede Germany fun oro ile okeere, Joschka Fischer so wipe orile-ede on nkepe fun ifagile gbese orile-ede Mozanbique eyi to fere to bilionu kan ati abo owo dola Amerika.

Minisita oro ile okeere na so wipe o ye ki won gbe igbese lori oro na lesekese paapa leyin omiyaleyaona eyiti o ti ba orile-ede na je.

Ni osu keji odun, die ninu awon ti Mozanbique je ni gbese fowosi idaduro odun kan laisan gbese sugbon ijoba Mozanbique so wipe ifagile gbese ni iba ti dara ju.

Nibayi sa, awon omo ogun ti awon orile-ede Amerika, Geesi ati Germany ko lo lati se iranwo ninu akitiyan akoyo ni Mozanbique ni o ti bere si kuro.
*BBCNEWS*

**Ajo CITES dabobo eja aye igbaani** **3mins. 59secs.**
Eja kan ti a mo si *coelacanth*, to je eja aye igbaani eyiti a ti ro tele wipe o ti parun patapata pelu awon omiran eranko aye igbaani ti a mo si *dinosaurs* ni o gba idabobo nigbati Ajo Agbaye fun Adehun lori owo kariaye ninu awon Eya to wa labe ewu iparun (UN Convention on International Trade in Endangered Species (CITES) gbesele owo ninu re. Apero nla olorileede adojo na eyiti won se ni ilu Nairobi orile-ede Kenya tun fohunsokan lati gbesele owo ninu malu okun orile-ede Australia kan ti a npe ni *dugong*. Ijapa okun ile Asia ti a npe ni *box* ati awon ijapa oni patako lese ti ile Afirika na ni won fi si ori akosile awon eya to wa labe ewu, apero na si seleri lati teramo idabobo won.
Ajo CITES tun fowosi igbesele olojo pipe to ti wa lori owo ninu erin, abuibutan ati awon ijapa okun. Adehun na ti fi aabo olorisirisi ipele sori awon eya eweko ati eranko to ju egberun lona ogbon lo.

Ipinnu lati dabobo eja *coelacanth* to ti wa fun irinwo egberun odun ko ni atako kokan rara. Akojopo *coelacanth* meji pere ni a ti se awari won nibiti gbogbo eja na to wa nibe ko ju edegbeta lo.

Awon onimo ijinle sayensi ti ri eya ara eja na ti a wu jade lati inu ile, won si ti gbagbo wipe o ti di awati pelu awon omiran eranko dinosaurs sugbon awon eja to si wa laaye ni won ri nitosi erekusu Comoros ni okun kariaye ti India ni odun 1938. Ni odun meji seyin, won tun ri awon eja miran nitosi erekusu Manado Tua ni orile-ede Indonesia.

Ibere wa fun awon eja na lati awon ajo to ntoju awon ohun isenbaye ati lati awon orile-ede nibiti won ti rohin eja na wipe o nse alekun agbara okunrin fun ibalopo. Pelu bi o se je wipe eja na die lo wa, awon afenifere itoju fe ki a gbesele owo ninu eja na to wa labe ewu iparun ati eya eja na ti a ba se awari ni ojo iwaju.

Awon asoju ninu ipade ajo CITES tun fenuko lati se agbekale ilana kan labe eyiti a o gba isowo laaye ninu awon ijapa okun ile Asia ti a mo si *box* ati ninu eya *urial* to je agutan egan ti a ma nri ni orile-ede mejo ni aringbungbun ile Asia.

Awon ikepe fun igbesele patapata lori owo ninu awon eja dolphin onimu-bi-igo ti okun dudu ati gbogbo eya agbonrin kekere olorun-didun ti a mo si *musk* ni won ko gba wole. Dipo re ni won se awon ipinnu to kepe awon orile-ede to je omo egbe lati se iwopale isowo ti ko bofin mu to nlo lowolowo ninu awon eya na.
*CNN.com*

**Igbesele isowo ninu ijapa okun si wa sibe ni orile-ede Cuba 2mins. 59secs**

Aba orile-ede Cuba lati ju okun igbesele olodun medogbon lori isowo ninu awon ijapa okun sile die ni o kuna ninu ipade Ajo Agbaye fun Adehun lori owo kariaye ninu awon Eya to wa labe ewu iparun (UN Convention on International Trade in Endangered Species (CITES) eyiti o sese pari ni ilu Nairobi. Ajo CITES ko lati jeki orile-ede Cuba ta awon akojo igba eyin awon ijapa okun ti a mo si hawksbill to si sowon gidigidi.

Aba na ni lati gba orile-ede Cuba laaye lati ta egberun medogun o le igba iwon igba eyin hawksbill fun orile-ede Japan ninu itaja eleyokansoso. Orile-ede Cuba nilo ifowosi lati odo iko meji ninu meta awon to wa si ipade sugbon o kuna pelu aami kekere nigbati orile-ede merindinladorun dibo faramo aba na ti awon mejidinlogoji dibo tako. Awon medogun ko dibo rara.

Orile-ede Cuba tun bere fun ase lati mu edegbeta hawksbill lododun fun tita lati inu awon omi re sugbon o fa ibere na seyin nigbati atako po pupo lori re.

Hawksbill le won to iwon mejileladoje. Igba eyin won si ma ni awon ila alawo osan, ofefe and kofi, eyi si mu ki won di eya ti awon eniyan fe julo ninu eya meje ijapa okun to wa laye. Igba eyin re ti won npe ni “bekko” ni orile-ede Japan ni won ma nlo fun awon ohun ona ati eso ara. Awo ara hawksbill ni won ma nsagbe lati fi se bata alawo.

Awon afenifere itoju gba wipe orile-ede Cuba ni ilana isakoso to dara fun awon ikore re sugbon won kilo wipe hawksbill je eya to wa labe ewu iparun to ga, ti won ba si gba owo ninu re laaye labe ofin eyi yio se irusoke ibere ti yio yorisi ijiodese re nibomiran.
Cuba ma nse ikore bi edegbeta hawksbill lododun sugbon igba eyin re ni won nfi sinu akojopo ti orile-ede nigbati eran ara won ma nlo sodo awon ara ilu gegebi ounje. Awon ijapa okun ti ngbe ninu awon okun kariaye fun irinwo egberun odun sugbon iye won ti lo sile pupopupo ni awon ewadun to koja lo. Ajo CITES gbesele

isowo kariaye lori opolopo ijapa okun ni odun 1971, o si fi awon eya to ku kun akosile na ni odun 1981.
*CNN.com*

**Ajo CITES fi ake kori wipe igbesele isowo ninu ehin erin gbodo tesiwaju 2mins. 45secs.**
Inu awon afenifere itoju dun si abajade apero ti awon egbegbe si Ajo Agbaye fun Adehun lori owo kariaye ninu awon Eya to wa labe ewu iparun (UN Convention on International Trade in Endangered Species (CITES) eyiti o waye ni ilu Nairobi ni orile-ede Kenya.

Bi ariyanjiyan to gbona tile wa, awon asoju si ipade fohun sokan lati fi edidi di igbesele kariaye lori isowo ninu ehin erin, o si ko awon aba ti iba yorisi idinku ninu idabobo to wa lori awon abuibutan *gray* ati *minke.*

Ninu igbese ti a ko fokansi, gbogbo ibere fun isowo ninu ehin erin ni won fawo won seyin ninu apero na. Awon orile-ede Botswana, Namibia ati Zimbabwe gba ibere won lati sowo ninu ehin erin pada. Ni idahun, orile-ede Kenya ati India fagile aba won lati se igbesoke akojopo erin to wa ni awon orile-ede meteta.

Gbogbo awon orile-ede na lo gba lati dawo ise duro lori awon ipinnu won yi titi ti won o fi fi ilana iwoye fun ijiodese ati isowo to dara lele.

Nibayi, aba alajose lati orile-ede Britain, Amerika ati Australia kuna lati ri ifowosi iko meji ninu meta lati fi eja yanyan funfun nla sinu awon eya to wa labe ewu iparun. Iru itosile yi ni iba fi idabobo akoko labe ajo CITES frun awon eya eja okun ti won npa fun isowo. Opo ninu awon atako si aba na da lori ariyanjiyan lori boya Ajo Agbaye fun oro Ounje ati Ise Ogbin tabi Ajo CITES ni ko ma se kokari isakoso awon eya eja to wa labe ewu.

Karen Stener to je oludari ilo awon eranko egan fun isowo fun Akojo Owo ni Kariaye fun Itoju Eranko (International Fund for Animal Welfare) so wipe: “o han gedege wipe awon ajo olusakoso ipeja ni awon elekunjekun ti kuna lati toju awon akojopo eja yanyan, eyi si je ohun to banininuje fun itoju eja yanyan.”

Bi apero na ti wa sopin, o han gedege wipe ipo awon erin dara pupo ju ti opolopo awon eya eranko to wa labe ewu iparun lo.
*ENN*

**Orile-ede Australia fi ehonu re han lori pipa ti orile-ede Japan npa abuibutan 2mins. 15secs.**
Orile-ede Australia ti fi ehonu re han si iroyin wipe orile-ede Japan ngbero lati mu eto iwadi re lori abuibutan to nfa iku dani gbooro si.

Minisita fun Ayika, Robert Hill so wipe o ya on lenu lati gbo ninu iroyin wipe orile-ede Japan nfe lati tesiwaju pelu pipa to npa abuibutan *minke* ki o si tun mu ise na gbooro de odo eya meji miran, iyen abuibutan *Bryde* ati abuibutan *Sperm* ni iha ariwa okun kariaye pacific.

Ninu oro re, Hill so wipe: “ko si idi to munadoko ninu imo ijinle sayensi lati pa awon abuibutan nitori ati se iwadi lori won.”
Hill tesiwaju lati so wipe orile-ede Australia yio fi ehonu re han ni kiakia ni ona olorilede sorileede ni ilodisi re si oro yi ki o si wa opin si pipa awon abuibutan. Orile-ede Australia yio tun se kokari fun alekun idabobo fun awon abuibutan ninu ipade olododun kejileladota ti Ajo Kariaye fun Abuibutan ni ilu Adelaide, ni iha gusu orile-ede Australia laarin ojo keta ati ikefa osu keje odun yi.

Orile-ede Japan lo nje eran abuibutan julo ni agbaye. Biotilejepe o ti gbesele pipa abuibutan ni onirepete fun isowo ni ibamu pelu awon ofin kariaye, orile-ede na si npa abuibutan fun iwadi ti imo ijinle sayensi. Eyi si nyorisi mimu abuibutan *minke* bi edegbeta lododun ninu okun kariaye Antarctic ati iha ariwa okun kariaye pacific: Eran ara won lo ma nlo sinu oja fun jije awon eniyan.

Orile-ede Japan jiyan wipe awon abuibutan minke po tobe ti won fi nmu irokeke ewu ba iruula awon eya eja miran, ati wipe o seese lati pa egbaa abuibutan lododun lai fi awon eya na sabe ewu iparun.
*CNN.com Nature*

**Orile-ede Egypt ati Thailand gba awon eru ehin erin to po 2mins. 33secs.**
Awon asobode ti gba egberun-o le-mejidinlogorun iwon ehin erin ni idiko baalu ni ilu Bangkok. Won ko ri eyi to po to be gba ri. Eniti won mu gegebi onifayawo na ni won ti ju sile. Ehin erin mejileladofa na ti iye owo re ju egberun lona mokanleladoje owo dola Amerika lo ni won ri ninu apoti meta eyiti a gbe lati orile-ede Zambia. Ehin erin na ni won fi pamo sabe eru awon okuta iyebiye ti won ko tii sise lo lori.

Mohammed Tailo to je omo iha iwooorun Afirika ni won damo gegebi onifayawo na nigbati o wa si idiko baalu na lati gba awon eru na. Won fi sile leyin na nigbati o ti gba lati kowe fi gbogbo ehin erin na fun ijoba Thailand.

Labe ofin orile-ede Thailand, eniti o ba ni eru ti a ko wole lona ti ko bofin mu yio bori ti o ba fi gbogbo eru na fun ijoba. Won ko iti pinnu lori ohun ti yio sele si awon ehin erin na sugbon iroyin so wipe won yio ba gbogbo re je tabi ki won ko fun eka ile-ise ijoba kan lati se afihan re.

Bakanna, awon olopa orile-ede Egypt gba eru ehin erin, iye ti won ko iti gba ri, ti iye owo re ni ita ju oke mewa owo dola Amerika lo. Ni ojo kokandinlogbon osu keta odun yi, Ile ise ijoba orile-ede Egypt fun oro Ayika kede wipe ehin erin mejidinlogorin ni awon ri gba ni ile ikerusi kan ni ilu Aswan.

Isowo kariaye ninu ehin erin ni won ti gbesele lati odun 1990. Ile ise ijoba orile-ede Egypt fun oro ayika to nse agbero ofin na so wipe lati aringbungbun ile Afirika ni won ti ko ehin erin na wa. Ile ise na so wipe onileikerusi kan ni ilu Aswan ti gba awon ehin erin na fun pinpin fun awon onisowo ehin erin jakejado orile-ede na.
*BBCNEWS/CNN.com Asianow*

**Won se awari Iresi iyanu 2mins. 33secs.**
Orisi iresi kan ti won fi imo ero nipa ajogunba eya gbekale eyiti o le se afikun ikore to bi iko marundinlogoji ninu ogorun ni awon onimo ijinle sayensi ni orile-ede Amerika ti se awari re. Irugbin titun na ni won siso loju re ninu apero kariaye lori imo ero iresi ni orile-ede Philippines.

Iresi je ounje kosemani fun bi idameta awon olugbe aye. Iresi titun na ni a lero wipe yio ko ipa pataki ninu igbogunti ebi. Eweko na ni awon onimo ijinle sayensi ni ile iwe giga Yunifasiti ti ipinle Washington ati awon oluwadi lori ise ogbin ni orile-ede Japan gbe jade.

Onimo ijinle sayensi to je asiwaju ise agbese na, Ojogbon Maurice Ku se alaye wipe eroja ajogunba eya lati ara agbado ni won fi sinu iresi na pelu eroja eya fun irugbin ti a mo si *pyruvate orthonophosphate dikinase*. Eyi se alekun iye ilana iseda aye fun imudagba eweko - iyen ona ti awon eweko ngba lati fi se aye won. Asewo ni oko mu ki ikore fo lo soke lona iyanu, biotilejepe Ojogbon Ku kilo wipe awon abajade na si wa ni iberepepe.

Gegebi oro re "Lati so di pipe, a gbodo se awon idanwo sii, ki ise ninu oko nikan sugbon ayipada sii pelu afikun awon eroja miran lati mu dara si." O wa fikun wipe o le gba won to odun meta si marun ki won to le fi iresi titun na le awon agbe lowo.

Nibayi, awon amoye ti Ile-ise Iwadi kariaye lori Iresi (International Rice Research Institute) so wipe alekun to nyara deba iye awon olugbe ti sare ba awon idagbasoke ninu iye ikore awon oka ti o ti waye laarin odun merinlelogbon to koja. Awon agbe gbodo gbe alekun milionu mefa o le oke marundinlogoji iwon tonnu iresi jade lododun. Won gbodo se eleyi pelu ile to kere si ati omi to kere si lati le mu ki ounje to peye wa ni awon ipele to wa nisisiyi.
*BBCNEWS*

## *Ifojusi*

**Awon onimo ijinle sayensi se agbejade awari lori bi emi se bere 2mins. 8secs.**
Fun igba akoko awon onimo ijinle sayensi le woye gbogbo ilana ajogunba eya eda eniyan lati wa awon idi tabi bawo ni a se le mo ki a si se iwosan awon arun. Aseyori yi na ni a le ro wipe yio ni abajade olojo pipe gegebi agbejade agba keke.

Eroja Chromosome 22, eyiti awon egbe onimo ijinle sayensi ni kariaye kan se itumo re, je okan ninu awon adipo eroja DNA merinlelogun to wa ninu seeli eda eniyan to ni ifitonileti toto lati so fun ni on to wa ninu eda eniyan. O gba egbe na ni gbogbo ewadun to koja lati fi se itumo gbogbo leta by milionu metalelogbon to wa ninu Chromosome 22. Ise na se afihan ogogorun awon eya eda ara eniyan titun.

O ju ogbon aidogba ilera lo ti a mo nisisiyi pe eroja chromosome na ma nse okunfa re, lara eyiti a ti ri ibaje okan, idibaje eya ara ati arun opolo "schizophrenia."

Igbese kini ninu iwoye eroja chromosome yio je lilo ifitonileti ti a ti kojo lati fi mo arun ninu awon eniyan. Bi a ba si nmo sii nipa awon itumo adiitu na, awon egbogi ati ona igbasewosan titun ni a lero wipe yio yoju. Nigbeyigbeyin a o se idiwon itoju aisan si bi eya eda eniyan kokan ba se ri gan an.

Gegebi oro Dokita Francis Collins lati ile ise orile-ede Amerika fun oro Ilera, to je alaga Ise Agbese lori Eda Eniyan na se so, "Eyi ni igba akoko ti ani ori kan to kun ninu iwe ifuninimo lori eda eniyan, o si yanilenu gidigidi."
*BBCNEWS*

**Ifojusona si osu kefa fun itupale ajogunba eya ara eda eniyan 2mins. 42secs.**
Agbeleko ikini lori adiitu ajogunba eya ara fun emi eda eniyan ni yio wa lori Itankale Ero Asisebiopolo komputa lori ero Ibanisoro, iyen Internet lati osu kefa odun yi. Ifilo yi lati odo Ise Agbese lori Itupale Ajogunba Eya Ara eda eniyan (Human Genome Project HGP) eyiti gbogbo ara ilu nse inawo re ti se idinku si ojo ti egbe alafowosowopo-se-nkan ti kariaye yio te iko mesan ninu mewa itupale ajogunba eya ara eda eniyan jade.
Ifilo na wa leyin awuyewuyewuye lori boya gbogbo ajogunba eya ara eda eniyan ti a ba tu pale ni ki gbogbo eniyan ni eto lati mo tabi ki o seese fun awon ajo oloko-owo lati dabobo awon imo na labe ofin.

Nisisiyi HGP ti se itolerawon lesese eyi to ju bilionu (milionu lona egberun) meji lo ninu bilionu meta leta to wa ninu itupale ajogunba eya ara eda eniyan.

O sese pe osu merin ni leyin to koja bilionu kan. Nitoto, ni ogun odun seyin, yio gba eniyan ni akoko to ju odun kan lo lati se akojopo egberun mejila awon ipile.Loni, iseju kan pere ni yio gba.

Gegebi oro Dokita Francis Collins to je oludari HGP, "Iroyin rere ni wipe a nyara lo sugbon iroyin to tun dara ju ni wipe awon oluwadi jakejado aye nlo imo yi lati fi se iwadi iru ipa ti ajogunba eya ara eda eniyan nko ninu ilera."

Ninu isele kan to farako eyi orile-ede Amerika ati Britain ti so ninu oro ajogbejade ikede wipe awon onimo ijinle sayensi jakejado aye gbodo ni anfani lati lo iwadi lori itupale ajogunba eya ara eda eniyan.

Pelu ifohunsokan wipe iwadi sinu ilana-eto ajogunba eya ara eda eniyan je okan ninu awon ohun to se pataki julo lati igba iwase, awon orile-ede mejeji tesiwaju lati so wipe lati le ri ileri kikun iwadi na, "imo ipilese lori itupale ajogunba eya ara eda eniyan ati itolerawon lesese ati ipinsi orisirisi re ni a gbodo jeki o wa ni arowoto gbogbo onimo ijinle sayensi nibi gbogbo laisi idena kokan."

*The Financial Standard/BBC News*

**Egbogi agbejako kokoro bakteria lo se idena awon ikolu to je mo kokoro-arun HIV. 1min. 42secs.**

Egbogi agbejako kokoro bakteria ti ko won to si wa yanturu ni o seese ki won fun bi awon omo ile Afirika milionu meji to nni awon ami kokoro arun HIV tabi ti arun kogboogun Eedi nitori o le dena awon afomo ikolu lona ara ko si gba emi la.

Ajo UNAIDS ati Ajo Agbaye fun oro Ilera (World Health Organisation) yio gbaniniyanju lati lo egbogi agbejako iredodo fukufuku ti a mo si cotrmoxazole. Ni apakan, eyi da lori awon awari egbe amoye kan wipe idaji ninu awon to ni arun Eedi to lo egbogi na lo ku, sugbon gbogbo awon miran to ni arun na ti ko lo egbogi na lo ku. Egbogi na le dena awon orisi iredodo fukufuku ti kokoro bakteria to nni ikolu lara eje ati ilana dida ounje nfa Ajo "Life Initiative", eyiti Ile-ise Aare orile-ede Amerika gbe owona ogorun milionu owo dola Amerika sile fun ti so wipe on le ra egbogi na fun orile-ede merinla ti oro na kan. Sugbon sa, ajo UNAIDS tenumo wipe egbogi na je ojuutu onigba-die ni, ati pe on ko iti pinnu iye ewu to wa ninu lilo egbogi na kakiri le yorisi igbaagbarasi lati owo awon kokoro bakteria tintintin to nfa arun.

*Associated Press*

**Awokose SAVANNA fi imole titun han lori iwontunonsi laarin eda abemi egan ati eda eniyan. 1min. 43secs.**

Awokose ori ero asisebiopolo komputa kan to le sotele iru awon ayipada ti yio wa ninu ayika ila-oorun ile Afirika to takoko yio jeki imo wa ni arowoto awon eniyan ilu to ntiraka lati koju isoro ilo ile ati isakoso eda abemi egan.

Awokose komputa na ni a pe ni SAVANNA. Awokose na eyiti Ajo orile-ede Amerika fun Idagbasoke ni kariaye gbe owo sile fun, ni won ti wa lenu e lati odun medogun seyin. SAVANNA ni awokose kini to ni agbara lati koju gbogbo orisirisi ilo ile ati eto imulo to dojuko awon agbegbe ti ijoba dabobo ni awon ile perese orile-ede Kenya ati Tanzania to lo salalu.

Gegebi Robin Reid to je amoye lori ilo komputa nipa ilolupo awon eda abemi ni agbegbe won, to nsise pelu Ile-ise Iwadi kariaye lori Eran-osin (International Livestock Research Institute (ILRI) to wa ni ilu Nairobi ni orile-ede Kenya se so, aini ona si imo to se gbokanle ti ge opolopo eniyan kuro ninu awon ipinnu to kan ojo iwaju won gbongbon. Nibayi, awokose na ni won nse agbekale re ni ajo ILRI.

Reid so siwaju wipe: "Ayafi ti a ba ri awon imo to dara to si je otito lati fi siwaju awon to nse ipinnu awujo ki

won le ni orisun miran lati da ipinnu won le, bikose be o ko le ri ohunkohun yato si oro oloselu to ro mo ohun to nsele."

Lara awon irokeke ewu si awon agbegbe ti ijoba dabobo ni ila-oorun ile Afirika ni ilosoke ninu iye awon olugbe, osi, ijiodese ati ojukokoro oloselu. Awon nkan wonyi ti lowosi ilosile iko marundinladorun ninu ogorun ninu iye awon erin to wa ni orile-ede Kenya.

Pelu SAVANNA awon ti oro naa kan yio le mo awon ikolu olojo-kukuru ati olojo-gigun ti iru iwa bi idako-ogbin, sisin maalu, ilosoke iye awon olugbe ati ile kiko yio mu wa.

Lowolowo, ILRI ni eto idanileko fun awon omo orile-ede Kenya, Tanzania ati Uganda lati se afihan iye iru isele eto imulo ati isakoso ti SAVANNA le koju e.
*CGIARNEWS*

**Asewo pelu taba igbo yio bere lori awon alaisan** **1min. 34secs.**
Awon asewo ti isegun pelu awon egbogi ti taba igbo wa ninu won lori awon alaisan to ni awon ikolu lile-sodi awon eran inu ago ara, ifarapa si egungun eyin, ati orisi irora to ga miran ni ijoba ile Geesi ti fun ni ase lati tesiwaju.

Ajo oloko-owo Glaxo Wellcome Pharmaceuticals, ti Ile-ise Ijoba Ile Geesi fun oro abe-ile fun ni ase lati se iwadi ki won si gbe awon egbogi to ni taba igbo ninu fun ifunni lati owo awon dokita, ni yio se awon asewo na. Ti won ba yorisi rere, won le yorisi mimu awon egbogi to ni taba igbo ninu wa repete laarin odun meta. Iwonba awon alaisan die ni yio kopa ninu awon asewo alakoko. Sugbon sa, a lero wipe awon eniyan bi egbaa kan ni yio darapo mo eto asewo na laarin odun meji si meta to nbo. Ijoba ti so wipe ti awon asewo na ba yorisi rere, on setan lati se atunse si Ofin Asilo Egbogi lati gba ifunni ni egbogi to ni taba igbo ninu laaye. Ajo Glaxo Wellcome ni ireti lati ta awon egbogi oniyanfunni lati owo Dokita nikan lati odun 2003.
*BBC NEWS Online*

**O seese ki imole oorun fa arun ebo-oju** **1min. 34sec**
Awon onimo ijinle sayensi ti se awari wipe isirasile si imole oorun le se alekun ewu lati ni arun ebo-oju. Awon oluwadi to woye awon olugbe ilu Sete ni orile-ede Faranse ri wipe awon egbaa ole edegbeta ati merinlelogorin eniyan to sirawon sile si imole oorun to ga tabi si itansan oorun ni o fi ilopo merin wa labe ewu ati ni arun ebo-oju ju awon ti ko sirasile si oorun. Bi isududu se nnipon si yio di itansan imole lowo lati koja ninu awo oju ki o si lo sara ate inu oju fun iriran. A ro wipe itansan alagbara to wa ninu itansan oorun le mu ki isududu awo oju tete sele.

Biotilejepe won ko ni imo pupo lori awon ona lati fi din ewu ebo-oju to ro mo imole oorun ku, Dokita Delcourt to je olori egbe oluwadi na, gba awon eniyan nimoran ki won ma yera fun isirasile si imole oorun ni ojo kanri, ki won si de fila tabi lo awo oju to su dudu. Ikolu imole oorun na ni a ro wipe o se akojo lerawon, besi ni isirasile nigba omode se pataki bi isirasile nigba agba na.
*BBC News Online*

**Orile-ede Japan mu Eto Iderun Gbese gbooro si** **1min. 46secs.**
Orile-ede Japan ti se alekun si eto iderun gbese re lati dariji iko adorun ninu ogorun si gbogbo eyawo ti won se fun awon orile-ede to talaka julo laye. Ifilo yi to waye ni bi osu melo saju igba ti orile-ede Japan yio gba Egbe awon orile-ede mejo to ni oko-owo julo laye ni alejo ni osu keje odun, ni o kan awon eyawo ti ko si lara awon eyawo iranlowo ijoba orile-ede na fun idagbasoke.

Eto iderun gbese na kan ogoji orile-ede ti eyawo won po gidigidi. Iru awon eyawo be ti iye re to bilionu (milionu lona egberun) kan o le okoolelodunrun milionu owo dola Amerika ni o wa fun idojuti ofo lori isowo tabi eyiti awon ajo ara ilu bi awon banki fun iko-oja-losi-ile-okeere ati ikojawole ya sita. Orile-ede Japan ti dari gbogbo eyawa ti ijoba se fun idagbasoke ji. Orile-ede na tun seleri idawo sii si Akojo owo Banki Agbaye fun iderun gbese, eyiti yio mu idawo re di igba milionu owo dola Amerika. Ifilo orile-ede Japan yi se imugbooro si si ileri to se ni odun to koja si ipade awon orile-ede alagbara mejo ni ilu Cologne, orile-ede Germany, nibiti awon orile-ede aye to lowo ju ti fohunsokan lati fun awon orile-ede to talaka ju lagbaye ni iderun gbese to to adorun bilionu owo dola Amerika.
*Associated Press*

**Awon orile-ede G.8 si ni ireti fun Adehun lori Ayika 2mins. 37secs.**
Egbe olorile-ede mejo (G.8) ninu eyiti ati ri orile-ede Amerika, Canada, Faranse, Itali, Japan, Geesi, Germany ati Russia pari ipade olojo-meji ni iha iwo-oorun orile-ede Japan pelu oro asokagba wipe awon lero lati fowosi adehun pataki lori imorusi aye nigbati yio ba fi di odun 2002.

Bi atako tile wa lati odo orile-ede Amerika ati Canada, nipa akoko wo pato ni ifowosi na yio waye, awon minisita fun oro Ayika faramo adehun kan to nkepe orile-ede Amerika lati din awon efin oloro to nfa imorusi aye si iye to fi iko meje ninu ogorun din si bi won se wa ni odun 1990. Orile-ede Japan ati ile Europe na yio se idinku oni iko meje ati mejo ninu ogorun si bo se wa ni odun 1990. Awon ajo oloko owo oko irinna ati epo robi ni orile-ede Amerika ti won wa lara awon to ntu eyi to poju ninu awon efin oloro na jade so wipe adehun na yio pa oko-owo awon ati oro aje orile-ede won lara nipa fifi agbara mu won lati na owo to po si lori irin-ise ati imo ero.

Awon onimo ijinle sayensi gbagbo wipe ilosoke ninu efin oloro $CO^2$ lati inu jijo epo ati awon ohun idana miran lati inu ile ni o nmu ayika ile aye gbona sii. Awon miran nkominu wipe awon yinyin ori oke to nyo ni ekun ariwa aye patapata ti a mo si polar le fa omiyaleyaona ni awon ile perese to yi won ka, nigbati oju ojo to gbona si ni awon ibomiran le yorisi ogbele to gbooro. Igbimo kan ti ajo agbaye gbe dide ti sotele wipe iwontunwonsi igbonatutu ni agbaye yio lo soke pelu ipele meji si mefa laarin ogorun odun sii ti a ko ba din itujade awon efin oloro na ku.
*Associated Press*

**O seese ki aseyori lori Egbogi kan se iranlowo**
**fun iranti opolo ninu awon arugbo 1min. 48secs.**
O seese ki aseyori kan lori ajogunba eya ara eda eniyan yorisi awon itoju ti yio mu ki okan awon agbalagba mu yanyan bi ti awon odo. Biotilejepe itoju titun na ni a sese danwo lara awon ekute, awon abajade re ntokasi wipe o seese ki iru itoju be waye fun eda eniyan.

Nigba pupo awon agbalagba ma npadanu agbara won lati keko ati lati ranti, sugbon awon onimo ijinle sayensi gbogbo wipe awon ti mo eroja ajogunba eya eda eniyan to nmu ki eleyi sele. Ninu awon odo eroja yi ma nse iranlowo fun ilana ikeko nigbati o ma nsise seyin ninu awon agbalagba. Sugbon nipa ‘pipana’ eroja yi ti a mo si KVBI, o ti seese fun awon oluwadi lati mu ki awon ekute to ti dagba se daradara bi awon odo ninu ikeko ati iranti. Awon oluwadi ni Ile-Ise Wolfson ni ilu London gbagbo wipe o seese ki awon awari won fun won ni imo lori awon ohun to nfa Arun to ngba iranti eniyan lo ti a mo si arun Alzheimer. Ni lowolowo bayi, ile-ise na ndan egbogi kan wo eyiti o le dena ise eroja na nipa lilo imo ijinle sayensi nipa ikolu egbogi ninu ara lati sin ikolu na je. Bayen, won le se agbedide horo oogun fun iranti fun awon arugbo.
*BBC News*

**Awon obirin ile Afirika ni a fojusi ninu**
**Ipolongo lati tako ifi-iyato-si** **2mins. 30secs.**
Ifi-iyato-si to nkoju awon obirin si wa gegebi ofin ni ile Afirika, sugbon sa awon ajafitafita nse ipolongo lati yi eyi pada ninu ipolongo jakajado ile na fun awon atunse.

Yiyan awon agbegbe ifojusi fun egbe obirin ni ile Afirika na fonilaya: iha ariwa orile-ede Naijiria, nibiti a fi ase fun nina awon iyawo, sugbon ki o ma si 'ifarapa to buru': orile-ede Ethiopia, to gbesele ipelejo awon afipaba-obirin-lopo ti won ba fe olufaragba won: ati awon asa ayebaye jakejado ile na eyiti o fi agbara ati ohun ini sowo okunrin nikan.

Sugbon gbogbo eyi ko se idilowo fun egbe ajafitafita fun awon eto eniyan na to fikale si orile-ede Amerika ti a mo si "Ibadogba Nisisiyi", eyiti o si ile-ise re kan ni Afirika si ilu Nairobi ni osu kerin odun lati se iranlowo fun akitiyan lati koju ifi-iyato-si. Ohun ti ipolongo na dale ni lati se ibewo iparowafun si ile-ise asoju awon orile-ede Afirika merinla ti won si ni awon ofin to fi awon obirin se eda onipo-keji. Ifojusi pataki ni lati mu ki awon omo ile Afirika ri imole, laarin gbogbo isoro miran to koju ile na, wipe akoko ti to lati mu oro awon obirin ni okunkundun.

Ipolongo na fa die lara awon obirin die ti o wa nipo agbara ni ile Afirika wa, lara awon ti a ti ri omo ile igbimo asofin ni orile-ede Uganda, Winnie Byanyima. O nlo pupo ninu akoko re lati se eto fun awon obirin ti awon ofin eya lori ijogun ti so di alaini bugbe mo. Awon opo titun ni awon arakunrin oko won ma nle kuro lori ile won leyin iku oko won. Orile-ede Uganda, gegebi awon orile-ede die miran, ti ri awon iyipada die. Awon obirin ni ijoko die ninu ile igbimo asofin, eyiti a ya soto fun won ninu ipin funni. Nwon tun ni ile-ise ijoba fun oro obirin.
*Associated Press*

**Monomono nkolu orile-ede Ethiopia lekeji** **3mins. 4secs.**
Ni odun medogun seyin, iyan gba emi awon eniyan to ju milionu kan lo ni orile-ede Ethiopia. Nisisiyi, itan tun ntun ara re so. Loni, awon onise aanu siro wipe awon milionu mejo eniyan lo wa labe ewu lati owo airiounjeje. Eyi to yorisi ikepe si iha iwo-oorun aye lati dide ni kiakia pelu iranlowo ounje, lati le yera fun iru opo yanturu iku kanna.

Gegebi Ethiopia si ti wa ninu ogun jija ni odun medogun seyin, bena ni o tun wa ninu omiran nisisiyi. Iyato nisisiyi ni wipe ogun aala ile ni pelu orile-ede Eritrea. Nitoto awon alase ni orile-ede mejeji ni won ti so fun wipe ki won gbe ija ti segbe kan lati jeki o seese ki won mu iranlowo ounje de awon agbegbe ti ikolu na wa ni Ethiopia.

Osise Ajo orile-ede Amerika fun Idagbasoke kariaye ba awon akoroyin soro leyin ibewo olose-meji si die lara awon agbegbe ti iyan na ti nja. Gegebi oro re: "Mo lero wipe egbe mejeji yio le wa awon ona, laarin ija won lori awon ohun miran, lati ro ti inilo ise aanu to ga, paapaa ni iha gusu orile-ede Ethiopia." Osise na, Hugh Palmer, so wipe idahun si ibere fun iranlowo oko la ona to dara ju lo si ibudoko-oju-omi Assab ni orile-ede Eritrea ni ko mu iwuri wa.
Ni ibere ose kini ni osu kerin odun, orile-ede Eritrea ti so wipe on gba ki won lo ibudo-ko-ojuomi na lati se ipinkiri iranlowo ounje. Orile-ede Ethiopia ko oro na danu bi oro isoju-aye. Orile-ede Ethiopia tun fi esun kan Eritrea wipe o ji opolopo iwon tonnu iranlowo ounje lati Assab ni awon igba to ti koja.

Oludari Eto Iranlowo Ounje ni Agbaye ti Ajo Agbaye, Judith Lewis so fun ajo BBC wipe awon nse gbogbo

ohun ti awon le se lati lo awon ibudo-ko-oju omi ti Djibouti ati Somaliland to si sile sugbon ti ko to.

Nibayi, ni awon ilu bi Gode, isiro eniyan bi irinwo lo ku ni osu keta. Opolopo ninu won lo je omode. Obirin kan to ni omo kan ti ara re ko ya so wipe ni osu meji seyin, on ni omo meta. O padanu meji ninu won laarin osu meji. Bi isoro na ti buru to niyi, a si nilo iranlowo lati yera fun ajalu eda eniyan bi ti odun medogun seyin.
*BBC News*

**Ogba awon Eranko kan ni orile-ede China yio ya orile-ede Amerika ni beari panda meji** **1min. 47secs.**

Ogba Eranko ti orile-ede Amerika to wa ni ilu Washington ti ntun ile beari panda re to sofo se lati gbaradi fun awon ayalegbe titun meji lati orile-ede China. Awon beari panda na ni yio de si ilu Washington ni odun to nbo nitori ogba na gbodo se atunse ibugbe awon beari panda, ki o yan awon eranko to fe ko si gba iwe ase lati ko won wole. Awon osise ogba eranko na pada lati orile-ede China ni osu to koja pelu iwe a-gba-lati-se-be labe eyiti orile-ede China yio ya ogba na ni beari panda meji. A si so wipe yio na won to milionu mejo owo dola Amerika lati ya awon eranko na, ti eya won wa labe ewu iparun, fun odun mewa. Awon onimo ijinle sayensi lori ogba eranko yio se iranlowo to po lati gba awon beari panda nlanla na to si wa ninu egan la. Awon omo ti awon beari na ba bi laarin akoko na si le wa ni ogba Eranko orile-ede Amerika na biotilejepe ohun ini ijoba China ni won yio je. Ni odun 1972, orile-ede China fun orile-ede Amerika ni beari panda meji, Ling-Ling ati Hsing-Hsing, awon ni won si di ohun ifanimora to gbajumo julo ninu ogba na titi di ojo iku won laarin ewadun to koja.
*Washington Post/Associated Press*

**Isakoso awon orisun Omi: Ilo ati Eto Imulo ni awon agbegbe ologbele** **1min. 31secs**

Opolopo awon ajo olomi ni orile-ede Jordan ati Iran ni o seto apero kariaye kan lori "Isakoso Awon Orisun Omi, Ilo ati Eto Imulo ni Awon agbegbe ologbele." Apero na to waye ni orile-ede Jordan ni o ni awon olukopa to ju ogoje lo lati orile-ede mejidinlogbon, ati awon to wa lati ajo elekunjekun ati ti kariaye mejo. Laarin awon akoko eto pataki mefa na, o ju iwe apileko merinlelogoji lo ti won ka eyiti o nse afihan awon koko pataki ti yio dari bi a o se ma se akoso omi ni ojo iwaju: ilosoke to ga ninu iye awon olugbe awujo, aini imoye to to fun awon ara ilu lori idaamu to le waye lori ipese omi, aisi awon ohun imusakoso to peye ati aisi ifowosowopo to ni ipele elekunjekun ati ni kariaye. Apero na kepe fun idasile igbimo alagbara kan ti yio ma koju owongogo omi ni awon agbegbe olegbele, paapa pelu bi awon olukopa se muratan lati tenumo eto gbogbo eniyan lati ni omi to to fun awon ilo to se pataki ati fun ipese ounje.
*Consultative Group on International Agricultural Research (CGIAR)*

**Abuibutan to gunle si eti okun ni orile ede Japan ti ku** **1min. 22secs.**

Abuibutan kan to to iwon tonnu medogbon ni o ku ni etikun aringbungbun orile-ede Japan biotilejepe akitiyan lo lati wakati de wakati lati gbaa la. Abuibutan na eya ti *Sperm*, ti o gun ju ese bata metaleladota lo, ni won ri ni etikun oniyanrin kan ni ilu Osuka ni arigbungbun etikun pacific to wa ni bi ibuso marundinladoje si ilu Tokyo. Gbogbo ara re lo si sile nitori iyo omi lo sile. Awon osise agbegbe ati awon afinufedo-jura-eni-sile fun ise lati agbegbe ati leyin odi ilu sise ni gbogbo oru lati da abuibutan na pada sinu omi. Nigbati won so wipe abuibutan na ti ku, awon onise igbala duro ni idakeje pelu omije loju won. Tomio Miyashita to je amoye lori abuibutan ni Ile-ise orile-ede Japan fun Ise ogbin, Isogbo ati Ipeja, so wipe o je ohun ti o sajeji fun abuibutan nla ti eya *Sperm* lati gunle setikun, ati wipe o seese ko je wipe iye ati mona re ti ra.
*Kyodo News Agency/Associated Press*

**Eroja ajogunba Eya eda eniyan se alekun
ewu arun okan ninu awon to nfa siga 1min. 19secs.**

Awon to nfa siga to ba ni eroja ajogunba eya eda eniyan to ti so mo awon arun to so mo ifasiga ni o dojuko ewu ilopo meji fun arun okan ju awon ti ko nii. Eyi ni abajade iwadi aipe yi kan to jade ninu atejade iwe iroyin atigbadegba kan ti a mo si *Atherosclerosis*.

Awon eniyan ti ko ni eroja GSTT1 ni iko ogota ninu ogorun ewu arun okan ti won ba nfa siga nigba ti awon to ba ni eroja na ni iko ogosan lori ogorun ewu.

Iwadi na ri eroja na ninu iko merin ninu marun awon egberun o le igba ati adorun eniyan ti won ye wo. Eroja GSTT1 na ni a lero wipe o je okun isopo pataki lati le mo bawo ni ago ara se nlo awon kemikali to wa ninu eefin taba. Eroja na ni won ti sopo mo awon arun to je mo siga fifa bi idibaje apo-ito.
*CNN.com*

**Iderun Gbese fun orile-ede Tanzania 41secs.**

Ajo orile-ede Agbaye fun Akojopo Owo ati Banki Agbaye ti kede edidi iderun gbese kan fun orile-ede Tanzania. Edidi na ni owo re to bilionu (milionu lona egberun) meji owo dola Amerika.

Banki Agbaye yio na owo to ju bilionu kan owo dola Amerika lo lori gbese na nipase ajo re fun Idagbasoke ni Kariaye. Iyoku ni awon ayanilowo olorilede pupo ati olorilede meji-meji yio fara ro.

Iye gbogbo gbese ti orile-ede Tanzania je ju bilionu merin ati aabo owo dola Amerika lo.
*BCC News*

**Ogbeni Bill Gates gbe Milionu metadinlogota
owo dola Amerika sile lati fi gbejako Arun Kogboogun Eedi 1min. 55secs.**

Oga patapata fun ajo Microsoft, Ogbeni Bill Gates ti seleri milionu metadinlogota owo dola Amerika laarin odun marun to nbo gegebi iranlowo lati le dabobo awon omode ni ile Afirika kuro lowo ewu arun Kogboogun Eedi. Igbeowosile na lati odo Ajo Amuludun Bill ati Melissa Gates ni o tii tobi ju lati odo ajo amuludun aladani lati se atileyin fun idena arun Kogboogun Eedi laarin awon odo.
Awon odo lo ko eyi to ju idaji lo ninu awon ikolu kokoro-arun HIV jakejado aye. Ajo Akojo Owo ni Agbaye fun Awon Olugbe (The UN Population Fund (UNFPA) ni yio na owo lori ikojopo awon odo fun idanileko, idanileko lori Arun Kogboogun Eedi ni awon ile-eko ati ipolongo ifinkanhan ti a doju re ko awon odo. Ajo Agbaye si ti yan Botswana, Ghana, Uganda ati Tanzania nitori ife-inu awon olori oloselu awon orile-ede na lati dojuko oro Arun Kogboogun Eedi.

Orile-ede Tanzania yio gba milionu merindinlogun ati abo, Uganda yio gba milionu medogun o le oke medogun, Ghana yio gba milionu merinla nigbati Botswana yio gba milionu mejo o din oke marun, gbogbo re je owo dola Amerika.

Eyi to ku ninu owo na ni yio wa fun owona fun ajo UNFPA ati awon ajo meji ti ko lowo ijoba ninu- ajo Eto fun Imo Ero to sedeede fun Ilera (the Programme for Appropiate Technology in Health) ati Asewariona ni Kariaye (Pathfinder International).
BBC News

**O seese ki won ma le fi koko orile-ede Naijiria ranse si ile okeere mo laipe yi** **47secs.**

O seese ki awon onikoko ni orile-ede Naijiria ma le ta oja won si ile okeere mo laipe yi. Eyi waye nitoripe titi di isisiyi, orile-ede Naijiria ti kuna lati yipada si lilo awon apo ti ko ni kemikali *hydrocarbon*. Awon apo na lo je eyiti o se itewogba ni kariaye fun didi koko fun ifiranse si ile okeere. Awon to nfi koko ranse lati orile-ede Naijiria si nlo apo idoho ti Ajo Onikoko ni Kariaye ti gbesele lati odun to koja.

*The Punch*

**Erekusu Taiwan yio se ifojusi Igbonriri ati Eya Ile apani ninu ibere re lati di omo egbe Ajo Agbaye fun Oro Ilera.** **1min. 56secs.**

Erekusu Taiwan setan lati se ifojusi Igbonriri ati Eya Ile buruku to sele ni osu kesan odun to koja nigbati o ba tun tiraka lati darapo mo Ajo Agbaye fun Oro Ilera (World Health Organisation (WHO). Osise kan so fun ajo oniroyin Agence France Presse wipe igbaradi ti nlo lowolowo lati lo Igbonriri ati Eya Ile na to won to ipele meje o le ikomefa ninu mewa lori ohun elo iwon janba na ti a npe ni *richter scale* gegebi ategun lati di omo egbe ajo WHO. Igbonriri ati Eya Ile na, to je eyi to lagbara ju ninu awon to kolu erekusu na ni orundun yi ni o mu emi irinwo le egbaa kan lo, o pa egberun mokanla eniyan lara o si so egberun lona ogorun eniyan di alainilelori mo.

Osise na so wipe “Ajo Agbaye ko nawo iranlowo re jade laarin wakati merinlelogun ti isele na sele ...... eyi tilekun mo Taiwan kuro ninu ajo WHO to je ajo to farako Ajo Agbaye, eyi ko si mu ise aanu ba awon millionu mejilelogun eniyan to ngbe ni erekusu na.”

Erekusu Taiwan, ti orile-ede China ka si ekun kan to ya lo sugbon ti won nduro de ipadabo re, ni won le jade kuro ninu Ajo Agbaye fun oro Ilera ni odun 1972, odun kan leyin ti orile-ede China gba ipo erekusu na ninu Ajo Gbogbo Orile-ede Agbaye.

*AFP*

**Ajo Agbaye fun Idagbasoke fe se idasile akojo-owo fun Imukuro osi ni orile-ede Naijiria** **1min. 19secs.**

Ajo Agbaye yio se agbekale Akojo owo fun Imukuro osi (Poverty Alleviation Trust Fund (PACTF) ninu akitiyan kan lati mu osi kuro ni orile-ede Naijiria. Eniti o se afihan eleyi ni asoju ajo na ni orile-ede Naijiria, Ojogbon Mkaya Kankuenda ninu apejo oloko-owo kan ti Ajo awon oloko-owo ti nsise ni orile-ede Naijiria ati ile Geesi (Nigeria British Chamber of Commerce).

Akojo owo na ni a o doju re ko sise igbelese fun awon ilana idinku osi nipa lilo awon afikun owo ti a toju fun ise oojo awon talaka ni awujo. Akojo owo yio tun fun awon eniyan tabi ajo to ba nife lati se igbelaruge awon eto idagbasoke agbegbe won ni anfani nipase awon ise awon amoye eyiti a se lati ba inilo won mu. Eyi na ni a tun fokansi wipe yio se igbelaruge ise ajo UNDP gegebi ajo ti a le fokantan to si munadoko ninu imukuro osi ati idagbasoke eda eniyan.

*The Guardian*

**Awon obirin orile-ede Spain wo inu iwe itan** **51secs.**

Luisa Feranda Budi ati Esperanza Aguirre ni won kede won gegebi Olori ati Agbenu so fun ile igbimo Asofin kekere ati agba ti orile-ede Spain ninu osu kerin odun 2000. Eyi so orile-ede Spain di ikarun ni agbaye nibiti awon obirin ti nse olori awon ile igbimo asofin mejeji. Awon miran ni South Africa, Bermuda, Belize ati

Jamaica, gegebi Egbe Alasopo awon Ile Igbimo Asofin se so.

Ni orile-ede Spain, o je igba akoko ti won yan obirin gegebi olori fun ile igbimo Asofin kekere eleniyan odunrun-le-mokandinladota, biotilejepe Aguirre ti nse olori Ile Igbimo Asofin Agba lati osu keji odun 1999.
*The Punch*

**O setan ko setan: Awon odo orile-ede Naijiria ni ohun lori ero asomagbesi redio** **2mins. 51secs.**

Ibanisoro fun Ayipada (Communicating for Change (CFC) awon olutejade iwe iroyin Change Radio ti se ifilole ere itage atigbadegba ori redio kan ti a pe ni *O setan ko setan*. Awon ere ori itage na ni a beresi gbe safefe lati ojo kini osu kerin odun 2000 lori awon ile-ise redio jakejado orile-ede na.

O setan ko setan nfi awon odo orile-ede Naijiria (awon ti ojo ori won lo lati odun merinla si mokandinlogbon) han lona to fa ogbon yo, ati imoye won to dayato lori inilo fun idagbasoke orile-ede na. Awon ere na fojusi iyanju ija, airiisese, igbeko, ayika, ilera ati eto oloselu gbogbo ara ilu ati isejoba rere. Awon oro yi ni a ngbejade lori ipilese awon italaya to nkoju awon odo orile-ede Naijiria lojojumo.

Gegebi oro Sandra Obiago to je Oludari Alase ajo CFC, "Ohun ti O setan ko setan wa fun ni lati je ategun fun awon odo lati ba ara won soro, ki a le gbo won, ki won si ri wipe awon ero won nlowosi ona orile-ede Naijiria si imupadabo sipo." O tesiwaju lati so wipe on to mu awon ere na dayato ni wipe "awon odo lo se e fun awon odo." Opolopo ninu awon osere ati osise ere na ni won je awon odo olopolopipe ti ojo ori won ko ju odun mejidinlogbon lo.

O setan ko setan je abajade iwadi to jinle lori agbejade re lara eyiti a ti ri ibaraenisoro legbegbe mejilelogun ti a se jakejado orile-ede na lori oro na. Ise na tun seto apejo pelu iranlowo awon egbegbe odo mokanla nibiti opolopo odo lati oniruru igbesi aye ba ara won soro lori ero won lori ipo ti orile-ede Naijiria wa nisisiyi, ati awon ireti re fun ohun rere ni ojo iwaju.

Nibayi, awon atolera ere na ni awon eniyan ti nsoro re daradara gegebi ere to lagbara to si so oju abe niko, eyiti o fi bi awujo se wa pelu opolopo ilodisirawon inu re han. Sugbon ju gbogbo eyi lo, awon atolera ere na nfi awon oluworan sile pelu emi ireti, o si ntoka ona siwaju ninu orile-ede to nfi taratara nwa ona idagbasoke.
*CFC*

**Iji lile Alajayika pa ogun eniyan ni Madagascar** **55secs**

Iji lile alajayika kan ti won pe ni 'Cyclone Hudah" ni o pa ogun eniyan to si ni awon ikolu buruku miran lara awon egberun lona odunrun eniyan miran ni iha ila-oorun ariwa Madagascar, gegebi Igbimo orile-ede fun Igbanila (National Rescue Council (CNS) se so. Awon isiro na ni o wa lati inu ibewo awon osise ijoba ati ti Ajo Agbaye si awon agbegbe ti iji na to ja ni ojo keji osu kerin odun 2000 kan.

Gegebi oro Adama Guido ti Ajo Agbaye fun Eto Idagbasoke nigbati o se ibewo si Antalaha to je olu-ilu ni agbaye fun eweko *vanilla*, "ko si ile ti ajalu yi ko baje."
*The Punch*

**Ijoba Oloselu tiwantiwa gba alekun si ni orile-ede Senegal** **1min. 12secs**

Awon ondibo bi iko ogota ninu ogorun ni o yan Abdou Wade ninu idibo fun ipo aare orile-ede Senegal ninu osu keta odun. Eyi je ajabori pataki fun ijoba oloselu tiwantiwa ni ile Afirika. Biotilejepe ninu akosile,

Senegal je orile-ede elegbe oselu pupo, a ti ma nse apejuwe orile-ede na bi alafarajo ijoba oloselu tiwantiwa nitori ko si idibo to tii yorisi ayipada ninu ijoba lati odun 1960.

Ni ogunjo osu keta nigbati aare to wa lori oye fi tiyiteye gba wipe Wade ti bori, on ni o di olori ijoba ile Afirika keta to se be laarin ewadun merin.

Lati igba ajabori yi, Abdou Wade ti seleri lati ri wipe ijoba oloselu tiwantiwa tubo fese mule ni orile-ede Senegal nipa gige iye akoko ti aare le lo lori oye lati odun meje si odun marun ki o ma si le lo ju akoko ijoba meji lo.
*The Economist*

**Awon Eto Eda Eniyan ni ile Afirika** **1min. 48secs**
Gegebi iwe iroyin alatigbadega *African Research Bulletin* se so, awon ajo afenifere ti ko lowo ijoba ninu ti nkominu wipe o ye ki a gbe igbese to sekoko lori ipo ti eto eda eniyan wa ni ile Afirika. Ni osu kokanla odun to koja ni ilu Kigali ni orile-ede Rwanda, akoko ise ninu ipade kerindinlogbon ti Ajo Ile Afirika fun Awon Eto Eda Eniyan (African Commission for Human and People's Rights (ACHPR) ni o wa sopin pelu akosile onikoko-oro merindinlogbon eyiti o bu enu ate lu awon iteloju ni awon orile-ede to wa labe ogun. Lara awon iteloju yi ni idajo oni-paja-wiri, ogba ewon ti ko dara fun eda eniyan, isikiri opo eniyan ati awon iba-eto-eda-eniyan-je, paapa fun awon obirin, awon odo ati awon agbalagba.

Awon oluwadi otito ni won yio ran lo si orile-ede Burundi, Djibouti, Kenya ati Sierra-Leone. Akokoko ilana ajo ACHPR lori eto awon obirin ni won yio fi ranse si olu-ile-ise ajo OAU pelu ibere fun ise sise siwaju lori re.

Ipade ketadinlogbon ti ajo ACHPR ni o waye ni orile-ede Algeria lati ojo ketadinlogbon osu kerin si ojo kokanla osu karun. Ibere to yanilenu ti wa lati odo olori ijoba ni orile-ede Rwanda - nibiti awon ibaje eto eda eniyan ti waye ni odun 1994 - lati gba Ile Ejo Ile Afirika lori Awon Eto Eda Eniyan ti a ndaba re ni alejo.
*The Courier*

**Ifojusona si Beijing ati Marun** **1min. 30secs**
Beijing ati Marun ni yio je ipade pataki ti gbogbo omo egbe Ajo Agbaye ti a pe ni "Awon Obirin ni odun 2000: Iwanidogbandogba Eya, Idagbasoke ati Alafia fun Orundun kokanlelogun". A o see lati ojo karun si ikesan osu kefa odun 2000 ni olu-ile-ise Ajo Agbaye ni ilu New York.

Ipade pataki ti ajo agbaye na ni yio se ayewo itesiwaju to ti wa ninu imuse Awon Ogbon Imusenkan to fojusi ojo iwaju fun Ilosiwaju awon obirin eyiti a faramo ni ilu Nairobi ni odun 1985 ati Itepepe Beijing funIse eyiti a faramo ninu Apero Gbogbo Agbaye lori Awon Obirin ni odun 1995. Ipade na yio tun ji roro lori awon igbese ati ise ojo iwaju fun odun 2000 ati siwaju.

Ipade yi ko jo ti Apero Beijing eyiti o fa awon olukopa wa lati gbogbo aye si orile-ede ti a ti see. Eyi yio je ipade ti a se ni olu-ile-ise Ajo Agbaye ni New York, awon olukopa yio si je omo egbe, awon alabasisepo awon ajo oro-aje elekunjekun, awon ajo Agbaye fun awon Ise pataki, awon Ajo ti ko lowo ijoba ninu ati awon Ajo Ijoba ni Kariaye.
*WomenWatch*

**Eredi Beijing ati Marun? 1min. 30secs.**

Ikede ati Itepede fun Ise ti Beijing ni won faramo ni Ipade Agbaye kerin lori oro awon obirin ni odun 1995. Itepepe na se afihan ifaramo kariaye si ifojusi iwani-dogbandogba, idagbasoke ati alafia fun awon obirin nibi gbogbo. O da lori awon ifaramo ti a se ninu Ewadun Ajo Agbaye fun Awon Obirin lati odun 1976 de 1985: Awon ifaramo to farako eyi waye ni apero to waye ni ilu Nairobi ati awon miran ti a se ninu awon apero gbogbo aye ti Ajo Agbaye ti a waye lati odun 1990.

Itepepe fun Ise so awon ifojusi fun ogbon imusenkan o si se alaye awon ise ti o ni lati waye lati owo awon ijoba, awujo kariaye, awon ajo ti ko lowo ijoba ninu ati awon ajo aladani Odun marun leyin Beijing, ipade pataki na ti osu kefa yio fun gbogbo awon ti oro kan ni anfani lati se ajopin ati ifiwera won iriri won. Won yio tun se atunse awon ifaramo ti teletele ki won si se awon titun miran. Won yio se ayewo awon idiwo ti won ba pade ati awon ise rere ninu imuse itepepe fun ise na.

*WomenWatch*

**Awon Ijoba dahun si Iwe Iwadiotito 1min. 35secs.**

Ni igbaradi fun ajo pataki to nbo idahun ti de odo Ajo Agbaye lati orile-ede merinlelogoje lori iwe Iwadiotito ti won fi ranse si awon ijoba lori imuse Itapepe Beijing fun Ise. Iwe Iwadiotito na eyiti won se lati fi gba ifitonileti lati odo awon ijoba ni won yio tu pale ki won si kojopo ninu iroyin ayewo ti won yio gbe siwaju ipade pataki ti gbogbo omo egbe eyiti a pe ni Beijing ati Marun.

Iwe Iwadiotito na je alapameta. Ni apa kini awon oludahun ni won ni ki won se itupale agbeyewo awon itesi ati iriri won lori imuse Itapepe fun Ise na. Apa keji fojusi imuse funrarare ti a ba foju wo lati ibi awon ilana ise ti orile-ede ati ni pataki iye oro ti won lo ati awon eto ti won gbekale. Apa keta iwe iwadiotito na da ni pataki lori imuse awon ohun mejila to je ohun ikalara fun Itapepe fun Ise na.

Eka fun Ilosiwaju awon obirin lo ko awon iwadiotito na sita ni osu kewa odun 1999. Nigbati yio fi di ojo kini osu karun odun 2000 awon orile-ede merinlelogoje to je omo egbe ati awon oluworan meji lo ti da esi pada.

*DAW*

**A yan alaga titun fun Igbimo Eleto 1min.14secs.**

Ni ogunjo osu kerin odun 2000, Igbimo to nseto Igbaradi fun Ipade pataki ti Ajo Agbaye na ti yan Arabirin Christine Kapalata gegebi alaga. Eniti on gba ipo lowo re ni Arabirin Roselyn Odera ti orile-ede Kenya to ti je alaga igbimo eleto na lati ojo kejidinlogbon osu kefa odun 1999. Arabirin Aicha Afifi ti orile-ede Morocco ni awon Egbe Ile Afirika ti yan gegebi Igbakeji Alaga igbimo eleto na, iyen ipo ti Arabirin Kapalata fi sile.

Nibayi, Igbimo Olugbalejo ti awon Ajo ti ko lowo ijoba ninu (NGO) fun Beijing ati Marun ni won ti gbe dide lati se kokari orisirisi akitiyan awon NGO ni ilu New York eyiti yio ma lo ni akoko ipade na. Igbimo olugbalejo na yio tun ran awon asoju awon NGO lowo nipa gbigba iwe ase iwoorile-ede. Awon eniyan to ba nife ni won ti ro lati kan si Arabirin Promita Sengupta lori ero ifi iweranse e-mail: psbeijing@earthlink.net.

*DAW*

## *Eto Awon Omode*

**Bi ketekete abila se gba awon ila teretere re 3mins. 22secs.**

Ni ojo kan to ti pe pupo seyin, obo Ilaburu nla kan to roro sokale kuro lori awon igi lati ma gbe ni eti bebe odo nla Umfolozi. Nibiyi lo se ile re si, o si wa kede fun awon eranko to ku wipe ti on ni gbogbo ile to wa ni ayika,

won ko si gbodo lo omi odo na. On nikan lo leto ati mu omi.

Okan ninu awon eranko pinnu lati koju Ilaburu onroro na. Eyi ni ako odo ketekete abila onigberaga kan to nje Dube.

Ni awon igba ti a nsoro re yi, awon ketekete abila je funfun balau bi esin inu itan isenbaye ti a mo si *Unicorn*. Dube laya o si ta Ilaburu laya si ija. Ilaburu to je ogbontarigi ninu opolopo ogun gba. O mo nipa ija gan an ni.

O so wipe: “Eni to ba padanu ninu ija na ni won o le lo patapata titi laelae si asale perese to wa ni irekoja odo na.” O si so fun ketekete abila lati wa si ogba ile on ni owuro ojo keji.

Ija na gun o si buru pupo. Awon eranko mejeji fi gbogbo agbara won ja, won si lo awon ohun-ija ti eleda fun won. Dube lo awon patako ese re ati eyin re to mu nigbati Ilaburu lo eyin re gigun ati iyara re.

Nigbeyingbeyin owo Ilaburu lo soke, o si ju Dube seyin sinu awon gedu to njo ninu ina ninu ogba na. Awon owo ina lile na jo kakiri ara o si ba awo onirun re funfun daradara je. Irora buruku na fun Dube ni agbara otun, pelu itapa alagbara kan o si gbe Ilaburu fo koja odo kolu awon apata to wa nibi oke kekere to wa nibe. Ilaburu jabo pelu agbara nla tobe ti apa na si wa nidi re titi di oni oloni.

Sugbon Dube na ti gba aami ayeraye. Ijoni lati inu awon gedu to njo bulabula ninu ina Ilaburu fi ila teretere si gbogbo ara awo onirun ara re to funfun bi ojo-didi. Sugbon boti-wu-kori o ti bori, lati ojo na lo ni odo na ti si sile fun gbogbo awon eranko na.

Lati igbana ketekete abila ngbe ila ara re kiri pelu ola. Nigbati a si le awon ilaburu lo si ori awon oke kekeke olokuta, awon ketekete abila ngbe lori awon ile perese, won si nlo won nbo si odo na bi o ti wu won.
*When the hippo was hairy*

## *Awon Oro Asokagba*

**Awon oro manigbagbe lori ayika ati idagbasoke**

> “Eda ko dabi wipe o le fi ohunkohun sile to je ehanna ati adayeba.”
> *Olwen Frost*
> Omo odun medogun lati orile-ede Barbados.

> “Fun awon igba ti a fi nduro de awon ohun iranti titun, e jeki a toju awon ohun iranti aye atijo.”
> *Victor Hugo*
> Onkowe ere itage ati iwe itan aroso, omo
> orile-ede Faranse, 1802 - 1885.

“Gbogbo eran ara dabi koriko, besi ni gbogbo ogo eda eniyan dabi itanna koriko.”
*Bibeli*
Peteru kini, ori kini Ese kerinlelogun si ikedogbon.

"Ti a ba gbiyanju lati fa ohun kan tu funrarare, wa ri wipe o so po mo ohun gbogbo to ku."

*John Muir*
Afenifere itoju iseda aye, omo orile-ede
Amerika to bere ilana Ogba Eranko ti
orile-ede, 1838 -1914.

"Kini anfani ile ti o ko ba ri aye to se gbe lati fi sori re."

*Henry David Thoreau*
Onkowe ati Alariwisi lori awujo,
1817 - 1862.

"O ku sowo imo ijinle sayensi lati se itankale imo wipe yiyan ki ise laarin awon ibi egan tabi awon eniyan inu egan, sugbon o wa laarin ojo iwaju eda eniyan to ni oro tabi eyiti o kuuse."

*Tom Lovejoy*
Igbakeji Aare Ajo WWF nigbakanri
fun Imo Ijinle sayensi.

"Imo bi gbogbo wa se lowosi idari emi aye sese nhan si opolopo wa ni, eyi si jasi ayipada miran ninu ero eda eniyan."

*Lewis Thomas*
Onkowe, Awon Emi seeli kan.